**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**AGBÁRA LÁTI ṢE ÌDÁJỌ́ (2)**
**OṢÙ KEJILÁ, ỌDÚN 2023**
Ìwé Mímọ́ kíkà: Dáníẹ́li 3
Ìjẹ́wọ́: Hèbérù 10:30

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Mo palẹ́numọ́ gbogbo ọ̀pẹ̀lẹ̀ tó n ṣọ̀rọ̀ lòdì sí ìlọsíwájú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Mo ṣe ìparun fún gbogbo ẹnubọdè àwọn ẹ̀mí onípá tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìtẹ̀síwájú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, rán àwọn ángẹ́lì Rẹ jáde láti yí gbogbo òkúta ìdènà sí ìgbéga, ìlọsíwájú àti ìgbésókè mi kúrò, ní orúkọ Jésù.
8. Olúwa, jẹ́ kí agbára pàrọ̀ ọwọ́ nínú (sọ ohun tí o fẹ́) sí ọwọ́ Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí iná Ọlọ́run jó okún ìyówù tó dèmí mọ́lẹ̀ sí ojú kan, ní orúkọ Jésù.
10. Mo túká gbogbo ẹbọ tí wọ́n rú lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
11. Gbólóhùn sátánì tí wọ́n ṣètò sínú òòrùn, òṣùpá àti àwọn ìràwọ̀ lòdì sí ìlọ̀síwájú mi, mo fagile nípa iná, ní orúkọ Jésù.

12. Mo yí dànù, mo sì parun, ìlànà ìkà àdàlù àlá ìyówù, tí ó sopọ̀ mọ́ ìlọ̀síwájú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ òkùnkùn, tó n dábù ìlọ̀síwájú mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
14. Mo kọ̀ láti kùnà ní bèbè ìlọ̀síwájú, ní orúkọ Jésù.
15. Mo de gbogbo itànjẹ àti àyídáyidà, tí wọ́n dojú rẹ kọ̀ ìlọ̀síwájú mi, ní orúkọ Jésù.
16. Mo sọ gbogbo ìgbógun tì búburú lòdì sí àlùmọ́nì àti ayànmọ́ mi di aláìlágbára, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo àjèjì òkùnkùn tí ó yímiká, tó n kóbá ìrìn àtitẹ̀síwájú mi, gba òjò iná, ní orúkọ Jésù.
18. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo àwọn ọ̀tá mi, tí wọ́n kórira ìlọ̀síwájú mi láìnídì, di gbígbésin lóóyẹ̀, ní orúkọ Jésù.
19. Olúwa, jẹ́ kí ìjì ìparun gbé gbogbo agbára ìkà mìn tó n mú ìjákulẹ̀ bá ìlọ̀síwájú mi, ní orúkọ Jésù.
20. Iná ajónirun Ọlọ́run, jó gbogbo òkùnkùn tó n jà lòdì sí ìlọ̀síwájú mi, ní orúkọ Jésù.
21. Olúwa, nínú ìbínú Rẹ, jẹ́ kí ìrúnú àwọn ọ̀tá mi tó lòdì sí ìlọ̀síwájú mi pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
22. Olúwa, rán gbogbo àwọn tó n ṣe inúnibíni ìrìn ìlọ̀síwájú mi lọ sí aṣálẹ̀ ìparun, ní orúkọ Jésù.
23. Ọlọ́run, dìde nínú agbára Rẹ, kí O sì gbógun dìde lòdì sí àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
24. Kìnìún ẹ̀yà Júdà, fa ọ̀tá àìrì tó n dí gbogbo ọ̀nà mi sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
25. Ọlọ́run dìde, rán ìdàrúdàpọ̀ sárìn ìkórajọ̀pọ̀ òkùnkùn, tó n dí rìkíṣí lòdì sí ìlọ̀síwájú mi, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo ẹni tó n pe títóbi mi níjà, Ọlọ́run dìde, fa gbogbo wọn lulẹ̀, kí O sì pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
27. Gbogbo ètò ọ̀tá láti fi ayé mi parí ìṣirò wọn, ta padà, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo agbára tó n wí pé rárá sí àwọn ìgbìyànjú rere mi, iná Ẹ̀mí Mímọ́, yà wọ́n lárọ, kí O sì pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.

29. Gbogbo àwọn tí ó fẹ́ kí ojú mi rí ibi, ẹ̀yin ángẹ́lì onípa láti ọ̀run, ẹ jù wọ́n sínú yàrá ìdálóró búburú, ní orúkọ Jésù.
30. Olùpa ayànmọ́ run, sun oorun ikú, ní orúkọ Jésù.
31. Àwọn ọ̀tá tó n gbógun ti ọwọ́ mi kí ó má baà ṣerere, Olúwa, da iná Rẹ sórí wọn, ní orúkọ Jésù.
32. Gbogbo òkúta ibi tí ọ̀tá n jù sí ìlọ̀síwájú mi, ta padà ní ìlọ́po méje, ní orúkọ Jésù.
33. Òkúta ikú, bá ọkùnrin alágbára ìyówù tó dúró sí ojú ọ̀nà mi láti lọ sí òkè, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo olùbá ayànmọ́ mi jẹ́, bẹ̀rẹ̀ siní jẹ́ ekuru títí tí ìwọ yóò fi kú, ní orúkọ Jésù.
35. Àwọn ọfà itìjú tí wọ́n rán láti pa ògo mi lára, ta padà, ní orúkọ Jésù.
36. Agun ẹṣin ìkà, ẹṣin ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, gbókítì, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo ọfà òkùnkùn tí wọ́n rán lòdì sí mi, ta padà nípa iná, ní orúkọ Jésù.
38. Olúwa, tú gbogbo agbódegbà ibi tí wọ́n rán níṣẹ́ lòdì sí ìlọ̀síwájú mi ká, ní orúkọ Jésù.
39. Àwọn agbára òkùnkùn, tí wọ́n yí àlàjá mi ká, ẹ sáré wọ inú kòtò ikú lọ, ní orúkọ Jésù.
40. Ònfà àìlèra, ogun jíjà àti orí burúkú, ta padà, kí o sì gbé ẹni tó rán ọ níṣẹ́ mín, ní orúkọ Jésù.